OFIN ENITI OBA FI OJU DI QBA AWOWO A WO

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

VOL. VII No. 342 LAGOS (SATURDAY) ỌJỌ ABAMẸTA DECEMBER 19, 1953. IYE OWO ELETI ỌFẸ KOBO MEJI (2)

## Awon Ti Ko Fe Ṣan Owo Ori Wewon

**Badagry** Awọn enia mokanlelogota ti awọn Ọlọpa ko nilu Badagry ninu rogbodiyan ti o sẹlẹ nigbati nwọn kọ lati san owo ori, gbogbo wọn li a dali ẹwọn.

## Ikede

A fi [illegible] ... 1954.

## Rogbodiyan Alafin Oyo Pari

**Oyo** Rogbodiyan kan ti o ti ṣelẹ lar'n Alafin Ọyọ ati awọn Oyọmesi ti ọrọ na dogun ti o si tun dode, ni awọn igbimọ loba loba rán Oba Olowo, Oba Ado Ewi, Ọba Ade'e Eko, Akinyele Balogun Ibadan, Ṣoye Balogun Ijẹbu Ode, lati tun lọ ba awọn ara Ọyọ soro.

Nwọn se 'pade na ninu ile ẹgbẹ Asiba Ijọyẹ, ẹsẹ gbogbo awọn Ijoye ati awọn enia pataki lo pe, awọn ara Ọyọ tun gba iwe ọjọ kini awa'u Alafin wipe ayafi bi Oba wọn ba le ṣowọ bọ iwe ohun meji la ti awọn fẹ wipe ki o ṣe ni ọrọ yio lo pari.

Alafin taku wipe gbogo o ọrọ na ni on fi ara mọ, ẹṣẹ ni, on ko gba wipe on soro ninu Iwe Irohin Eko pe awọn Oyọmisi wa bẹ on ekeji nitelọ on ko gba ọrọ igelu ninu ọgba afin oṇ.

## Eni Foju Doba Awowo Awo

**Ibada** Awọn igbimọ Lọ a-loba yio se ipade igbimọ kan nilu Ibadan laipẹ yi, lati se ajumoro nipa ẹni ti yio tun joye oba, nigbati ọba kan ba waja.

Ninu ipade na ti nwọn o se ni ọjọ Atalata 22nd Dec 1953, ẹsẹ gbogbo awọn ọba, Ijoye ati awọn Balẹ ti o loruko ninu igbimọ awọn lọbalọba ni nwọn fẹ ki o peju.

Olukuluku awọn Ọba yio ka iye awọn idile ti o njọba ni ilu rẹ ati idile ti Ọba yio tun kan.

Ofin ti o wa fun yiyan Ọba, Balẹ, tabi ijoye ni yi. Enikeni ti o ba fi ara rẹ joye tabi ti o jẹki awọn enikan fi on joye lọna eru, laiṣba aṣẹ lọdọ Aṣoju Gomina.

Tabi ti oluwa rẹ nbọ ẹniti gbogbo ilu ti yan fa kokowa, tabi ti o de fila faora rẹ bi o si ṣan bi Ọba oluwa rẹ lẹgbadi efin, ninu ki o san ẹd gbẹta pọun tabi ki o lọ si ẹwọn ọdun meji.

Lẹhin ti oluwa e ba ti jiya tan, ko wa kuro ede na lọ si ibomiran nilẹ Yoruba.

## Okuerin Kan Lo Sewon Nitori Panla

**Apapa** Okuerin kurum kan ti o nṣẹ nian ọkọ oyinbo kan ti o ke ẹro ẹja Panla gunlẹ si Apapa, ni Kurumọ na ara ilu Liberia le ji Panla ra ọrọ yẹ ti awọn Ọlọpa si ka o awọn yi gbe Kurumọ ẹdere ni de iwaju Idajọ ni Kotu Apapa.

Adajọ bere lọwọ Kurumọ na wipe, ninsinyi ọrọ ni wọn so ati yi, kini ohun ti o fẹ so si awọn kọ fi ni pe si ẹwọn.

O dahun pe, Gbarayba Ijiye ko nṣe ilu on, ko si lọ fi igbadun ara on bi na ba lọ si ẹwọn. Aon fe pe adajọ, o ni ki o ṣe san Pọun mẹrun tabi ki o lọ si ẹwọn ọsu meji.

## Baba Eso Ikoyi Salaisi

**Oyo** Gbuke ni a gburo iku Alaijẹluwa Onikoyi ọba ilu Ikoyi ile, on ni baba ẹ bi Ogbeni Eso Ikoyi ti o ngbe 62, Kosoko Street ni Eko.

Ojo eti rẹ to ndorin, aisan ojo die lo mu lo yi. Atiide iku li a nso aja morun, bi iku ba de, a gbe aja soran a mu emọ lọ, a dila fun Onikoyi lẹjọ ti iku kan ile rẹ lati wa, nigbati ẹbọ gba Eku, o kọ ko ru, nigbati o gba eiye o ko ko ru nigbati ẹbọ gba Akalamagbo o kọ ko ru. Ẹbọ gba arọ gidigba lalẹ, odo o kọ ko ru, Iku wa yo olugbore, o dile Onikoyi, ẹjẹ pe ti Ọba Ikoyi ti nda Eku, Ayan! o ri iku da Onikoyi.

## Owo Ori Da Nkan Sile Ni Ilaro

**Ilaro** Awọn ara Ilaro kọ wipe awọn ko ni san Capitation tax owo ori nitori ko ye wọn rara bi owo ori ti se goke rẹṣẹ.

Nigbana ni Ajẹlẹ Abẹokuta ba lọ si Ilaro lati la a ye wọn; awọn awọn apakan enia ninu awọn ara Ilaro sọ wipe Iro sile mewa ahọ ni awọn yin san, awọn elomiran ni deba sile mẹdogun.

Ajẹlẹ na ṣakiyesi wipe awọn enia na ṣe adoyi ka on ati pe, Ilafara pẹlu awu li o ori O sọ fun awọn enia na wipe odara bi awọn ko ba gba ki awọn toke kakia.

Sugbọn awọn enia na kọ lati tuka, nwọn si nṣu rẹnyiranyi, ẹyi lo mu oyinbo na lati yinbọ Pamọlẹkun oju ni bẹrẹ si ta awọn enia tobẹ ti nwọn fi ju okuta lu oyinbo na a i awọn Ọlọpa.

Oyinbo na tun yinbọn Pamọlẹkun lori akoji ki awọn ara Ilaro to tuka. Nwọn se Ọlọpa kan lese, enia meji si pese ninu awọn ara Ilaro

E KA IWE IROHIN Eleti Ofe

## Ikusiru Nibi Ise Reluwe

**Eko** Agburo ikusinu kan nibi Ise Reluwe ni Mechanical Department wipe, awọn alase wọn a me fi eni ehin ṣe eni iwaju nipa gbigbe ọmọ ise soke goju oga re lọ, Ri awọn ba mba ṣayi le ko le si sofesi kan ninu ise na.

Ohun ti o dara ni wipe eniti o ye ibe lo ye ki a fi ṣe e iyen ni wipe, eniti o ti ṣe lọọ iṣẹ yen lo ye ki a ma apade alude ise na, tabi eniti o mọ ise na deradara ni e la mu ilọsiwaju wa s'nu iṣe na.

E Ka Eleti Ofe



# ELETI QFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS; CABLES & TELEGRAMS
62, Kosegu Street, Lagos "ETI-QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 21376

VOL. VII No. 342 LAGOS SATURDAY DEC. 19 1953


## Keresimesi Qdun De!

Ni akoko ti ọjọ diẹ si loni, olukuluku eniyan ti Olorun ba da ẹmi rẹ si lode aiye lati tẹ ọjọ 25th Dec 1953 yio bẹrẹ si ma gbo ohun orin ti awọn Oloko yio ma fi ilu ṣe bayi pe Ke-re-si-mi-si Odun de, Odun alowo, ati orpolopo iru orin bawọnni ni a o ma gbo kakiri ilu.

Akoko ati igba asure tete, beni ko dure de enikan. Bi a ba boju wo ẹhin a ti aṣe Keresimesi ti ẹsi, yio dabi ana loju oluwa rẹ ilẹ ẹsu. Ile ti nmọ, Bẹni olejọ nkan, Eniti o je gbese ti o nda ogorun ọdun, ko ha mọ ẹgberun ọdun na li o mbẹ lẹhin ilẹkun yi. Bi o ti wu ki o pẹ to, Ogorun Ọdun mbọ wa ku ọla, loju awa ti a mbẹ loke erupẹ loni. Ọsu mejila ti jina loju wa ju ki o to pari, a bẹrẹ si ma daba wipe, ago re igba, ago se awo, beni ago ni se ikoko baba iyawo.

Li ọsẹ ti o mbọ yi, ni a o bẹrẹ alaye ọdun Keresimesi, a fi eyi yi ki awọn Aṣoju wa ati ọkawe wa ni Koriyo ati ni Imale, wipe awọn ku ipalẹmọ ti ọdun na yio yabo fun gbogbo wa, ọdun awọ ọdun ẹmọ ati ọdun alafia ni ki a ma ri.

Bi enia ba mọ rere, jẹki o ma se niwọ, ati ore ati ika, okan ko ngbe ki Olorun ki wa kun ẹniti yio ma ri ojurere rẹ li ọdun ni.

## Onisuru Ni Oba Ye

Ololo, Funmi laye kekere kan lati dahun si ibere Ogbeni Y.A. Komolafe ara Ike Oye ti o mbere eniti Oba tun tosi larin Onisuru ati Arẹwa I hio ti Jagun-jagun bu pẹhindẹ?

Loju temi Ogbeni Onisuru ni Oye na ty si, aitori awọn apowe bayi wipe Onisuru lo nse oko Omoba Alahoso, ati wipe Ibinu ko da akan Suru ni baba iwa

Emi ni
J. Adekola

Ara Kumasi


## A B C Baby Mixture

Egbogi yi dara lopolopo fun awọn ọmọde kekeke ti arun Iba ma mba ja tabi arun giri tabi bi ọmọde ba nfẹ bu ebio, tabi bi ọmọde ko ba ri igbẹ ya deradara tabi bi o ba nso, o dara pupo fun ọmọ ẹlomunrẹn. Bi a ba nlo loorekoore, yio fun ọmọ na ni alafia ewo poku ni.

Igo kekere 3/- Igo nla 5/-

**BANKS STORES**

12, Market Street, Lagos

P O Box 75. Lagos Nigeria

NOW AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS DISTEMPERS, SAFES Etc.

Just write, Call, or Phone 21572

IKORODU TRADING COMPANY

20/28, Balogun Street, (P. O. Box 395) Lagos, AND NEW COURT ROAD IBADAN

Just Arrived

Rubber Sheetings

ITẸ QMODE

MARMITE 2 ozs
" 4 "

ALAFIA BITTER

Thompson's Blood Tonic

To Clear at reasonable Prices

Call at

**Alafia Medicine Stores**

16, Idumagbo Avenue, Lagos.




*To every man of spirit the right to prove his worth in the job of his choice is a dearly cherished ambition.* In the free society of modern West Africa many are finding their opportunity with The United Africa Company which sets no limit on the promotion to which any of its employees may attain. Decision to appoint a capable man to a position of the highest responsibility is influenced solely by his ability. To-day, nearly one in four of the West African Managerial Trading staff is an African, with full managerial status and occupying a position of trust and initiative in the service of the Company and participating in every important aspect of its administration. The United Africa Company actively encourages the advancement of every one of its employees and recognises with satisfaction the rapidly increasing number of Africans assuming positions of responsibility in all branches of its organisation.

**THE UNITED AFRICA COMPANY LTD**

# Awon Eriwo Nipa Ohun Jije

Lati Owo ESO IKOYI

Nigu ohun gbogbo ti a nse ena lode aiye yi, eyiti a nfi owo ara wa fe lo poju ninu re, nigbati a ba si ngba ero afowofa wa a o ma ba Olorun wijo. Igba ila meji ti o dojuko ara won, eyiyi ni orun ati ile. Ofin mbe li orun ni ibi awon emi airi, bakanna ni ofin mbe li aiye nile aiye.

Awon ofin ti o wa fun ile aiye, awon baba wa ti o se wa sile ni Olorun fi han, on ni nwon npe ni Eriwo Mase. Nipa ofin ti orun awon Oyinbo ni Olorun fi eyini han. Ofin ti orun si yato si ti ile aiye. Ofin ile aiye pe, o si pe orisi meji (a) Ofin ti Eleda (b) ati ofin ti eda. Ofin ti eda, ofin ti Eleda ni a npe ni Eriwo ti eda papa ni a npe ni Ikilo.

Jeki akoko ba ara wa so die nipa ofin ti Eleda, nipa ohun jije (a) Li akoko Osupa, bi enia ba gbe nkan jije si ode gbangba ti ako si fi nkan bo o lori, tabi omi inu mo li ase be ti osupa si ran sinu re moju. Bi ile ojo keji ba mo ti eni kan si mu ninu omi na tabi oje ninu nkan, bi o ti wu ki o pe to, oluwa re yio si were ki oto ku.

(b) Bi agbalagba ti oti mpimo tabi ti o ti wo ehinrin ba ngbe ohe si o o je, tabi ti o njenu ninu ikoko tabi pann ti a ngbe kana, tabi ti onyo nkan je lori ina, arun abe tabi Igbatode yio ba luwa re ja.

Bi enikan ba ofe mu omi ti o si ri omi die nibikan sugbon nitoripe eyini ko to fun mimu nipa be, o tun bu omi miran kun u, Tabi bi enia ba ofe we, ti o mbe nile ko to nipa be oluwa re bu omi miran kun, o wa lo fi we arun ehun didun tabi arun. Wolewo ti yio ba oluwa re ja.

(e) Bi enia ba jo, eniti o ma amu omi li oru oganjo, bi oluwa re ba nse nigba gbogbo arun oju didun yio ba oluwa re ja, sugbon bi oluwa re ko ba ye se, yio fo loju patapata.

(f) Bi eni ba njeun lowo, ti okele oka tabi eja ba bosile lowo oluwa re, bi o ba tun mu oka na tabi eja re, abiku omo yo oluwa re lenu.

---

# Iye Enia Ti O Mbe Niilu Nwonyi Niyi

**Ekiti** Iwonyi yi ni awon enia ti o mbe ni ilu nwonyi nile Ekiti enikeni ti o ba si fe mo iye enia ti o mbe nilu tire, ki o kowe wa.

Aiyede Ekiti ati agbegbe re je 8'647. Aramoko ati agbegbe re 13'282 Efon Alaye ati Ipole je 14'468 Ijero ati agbegbe re je 46'701 Ikere Ekiti nikan je 35'584. Iyole ati agbegbe re je 29'473 Ogotun nikan je 4'468 Imesi Otoia Oke nikan je 6'063 Osi nikan je 3'78°, Ilu Otan ati agbegbe re je 20'094 Okitipupa nikan je 150'185 Ijo Apoi ati agbegbe re je 13'565. Ika ati agbegbe re je 93'462 Ondo nikan je 24.'099, Ilu ti o wa ni agbegbe Ondo je 111'359 Owo nikan je 224'793 Akoko nikan je 145'478 Arigidi ati agbegbe re je 20'871 Iran nikan je 4'580 Ogbagi ati agbegbe re je 9'200 Oka nikan je 28'524.

---

**Polowo Oja Re Si u Iwe Irohin Eleti Ofe**




# Lagos Belongs To The West

# Irohin Lati Ilu Okere

## Jagba Meji Se Owo Aiyederu

**Ibadan** Awon agbalagba ti o nṣe oun wipe, bi aba dagba ko se ogun ni jija ati wipe agbalagba ti oje owo re tan ni ngoji Odun, a be si kotti ti iwe were were sife, osiju pe ko le gbon titi lai lai. Awon omo meji kan ti ojo ori won ti le ni ogoji odun ni nwon tun dim le, ti awon lo se aiyederu owo Koiteri, tori nigbati Olopa lo ye ile won wo, nwon ba wo Kurenci Poun kokan bi merindilogun le ni gba Poun £216 ti gbogbo re je aiyederu.

Adajo wa won titi nigbati o ri wipe awon okun na jebi, oni ki awon le si ewon Odun merin merin. Sugbon won so fun Adajo pe awon be ki o je ki awon lo se ewon na ni ilu Abeokuta.

## Ilpapa Eleko Jona Raurau

**Obalende** Ni ojo ojo Monday to koja lo, ni a ri ti gbogbo oju orun pon we, ti mo lo awon Panapana, ana ere ogongon lo si apa ona Obalende, nwon si bere si lo ipase ma yi lo titi nwon fi de Apapa Eleko.

A gbo irohin wipe awon omode ti o nfi takat sere ti o si to lo si ori orule, ki o si to di on ti odidi ile mejo ni lati jona. Adupe lodo Olorun fun wipe enikokan ko jona s nu ile na.

A gbo wipe mo ni awon Panapana fi ero won fa omi lati Obalende lo ti pa ina na si Olorun gbowa kuro nibi jamba ina.

# Awon Omo Eko Se Ipade Nila Egbe

**Eko** Awon omo Eko ti a bi ti a si to nile Eko bi awon egba mefa ati awon Loye won se ipade gbogbo gbo kan ninu ile Egbe Ebingbesi nipa oro ilu Eko yi.

Gbogbo won si fi enu sokan wipe Eko yi, Lagos ti ile Nigeria ti ile Yoruba ni Yoruba lo to e do, beni awon Yoruba lo si ngbe inu re ki Oyinbo to de ati titi di isisiyi awa Yoruba lo ngbe inu re ki awon kogbede to wa se atipo ninu re.

Awa gegebi ara Eko, ko ni gba ki enikan tolu wa yan wa mo ebi nitorina ki Ogbeni Lyttleton ma ero na kuro lokan re nitori pe ile yoruba ni ilu Eko nje.

Awon Egbe kan ti a npe ni egbe Isedale ilu Eko ti kowe ransi silu Oba wipe, awon ko gba wipe ki enikan ya ilu Eko soto kuro larin awon yoruba omo iyawa yoku, Nitoripe Eko mbe larin ile yoruba, on si ni ori fun gbogbo ile yoruba, Bawo ni a ti se le ge ori kuro l ara yoku ylo le duro.

# Itije Atimu Ni O Gbemi De Eko Bayi Ni Omiran Alakuku Wi

**Eko** Ogbe bi itan ti a ti mu ori ka ni inu iwe itan awon Omiran, a gbo pe bi ebi ba npa Omiran nigba laelae awon o lo si oko agbe kan, nwon o ko adota malu si ejika otun, nwon o ko adota enia si ejika osi. Gbogbo awon Omiran igba na ti pare kuro li aiye.

Sugbon Omiran titun ti o ti le ile bo jade larin awon Ibo ara ilu Arochuku, ngbo pe nigbati ijoba dan agbara re wo, nwon wakiyesi wipe oni karufi rojo, nipa bayi nwon gba die ninu agbara.

Lori eyi ni omiran na nsoro le lori, wipe nigbati ijoba gba agbara on tan ti on ko lagbara mo lati else ti on ko si le rie, lo si ona jinila, ijoba ni lati ba on wa akan ti on yio je onje onia mefa ni on oje lekan.

Ki ijoba fun on ni nkan gegere ti on yio ma fi rin ti a ajo lo wa onje o jo on bi ijoba ko ba fun on ni onje.

# Imoran Fun Eyin Ibiyamo


Eyin abiyamo e wa ra **'Omorela'** O dara pupo fun awon omode

A mo je ki omode ti orun sun daradara, o dara fun otutu, Iko, ati oyinrin aruo mirin ti o ma nba omode ja ni asiko yi. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN
ni lodo

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST

10, Victoria Street Lagos.


# Aremo Oyo Ko Gbodo De Oyo Mo

**Ibadan** Aremo Oyo ti a ti ngbaro re lelelele nilu Oyo wipe, o nyaju si awon ijoye baba re, ati wipe, a ma ba awon ijoye ti o nse wole wode bara re tobe ti o fi di ohun ti awon ara Oyo ko fi ni isbekele si mo.

Nigbati o si ole da bowubowu sile ni ilu Oyo, ni ijoba ba se ise wipe ki a wa kuro nilu.

Lehin ti o ti kuro ni ilu tan, o ran lo fi iwe si kotu wipe on ko jebi de bi nwon le fi wa on kuro ni ilu o gbe ejo re lo siwaju Onidajo ag a Adaonda fun ayewo.

Ewon merin ni Aremo fi san Oyinbo Ajele ati Gomina. Ninu gbogbo esun merin na, nigbati awon amofin ti Aremo ati ti ijoba bere si ba ara won jiyan, Adajo na ri wipe gegebi ofin Aremo inoi gba gbo oro na, nitorina ki Aremo lo san ogun poun ati ogun sile fun Ajele loto ati fun gomina loto.

# Moto Kan Se Jamba Ni Idanre

**Idanre** Oko moto kan ti a npe ni moto Ayadi lo se jamba kan lojo Oja Alade, nigbati o nko awon ero lati oja na, gere ti o yoju si igboro Idanre lati odo kan ti a npe ni Ojo, ibe ni moto na gbe ti se jamba na.

Opo enia ni moto na pa lele, ni wa ra ngen, nwon ti ku nwon enia ti moto na se ni jamba o si ile Alaruo ni Akure, sugbon adupe lowo Olorun wipe a koiti gbo wipe enikan nlau won salaisi.

Ohun ti a gbo wipe o fa sababi ti moto na fi se jamba ni wipe idakoduro (Brake) oko na ti o je. Orere ba ti se fun eniti o ni moto pe idakoduro ti je sugbon ko ya si.

Oro yi mbe ni lowo iwon Olopa nisisiyi, nwon nwadi iwo


Awon ti o nse isegun ehin fi han wipe, ogun ti Colgate ti a fi nfo ehin ko nje ki ehin baje




Je nfo ehin Colgate lati fi pane orun hureku nipa fifo ehin ke ki o ma ba baje






**SEWING THREADS**

100 yds thread in wooden reels 10,000 5,000 yds thread in wooden cones 10,000 yds Looper thread comes various colours in Cotton and Art Silk

## Kini Hwon Onkawe Wa Nro

### Ibukun Ni Iranti Hwon Oku

Awọn enia nwọnyi jẹ awọn ti o mba wa ṣe ilu Eko yi gbigba kan ti sug ọn loni nwọn ti di ata Eropẹ Diẹ ninu wọn niwọnyi

Rev. Bishop Melrile Jones ku ni 1941.
Sanni Idowu of Akeeri 1943.
Jacob Olukoya Ijẹbu Ifẹ 1939
Yesufu Baba Egbẹ Ijẹbu Od: 1941
Daddy Otẹ Ijẹbu Ife 1936
" Faro " " 1936
Sanusi Afapé baba Arigo Eko 1941
Bisiọla Ogunbiyi Ajiṣọmọ 1940
Daddy Cardoso Igbasere Rd 1940
Hezekiah Davies Serafu 1940
Dada Adesigbin Eko 1935
Rev Gansalo Eko 1942
Rev Bishop N.A "Onatola 1942
James Ọdunsi of Ijẹbu 1937
Loya Victor A Kayọde Eko 1938
O. Fadejimi Eko 1940
Oke Adesigbin Alias Mojọ Eko 1942
Madam Rachaole O. Apọrua Eko 1940
S.G. Iroko Eko 1935
Daddy Gay Eko 1935
Ṣobọ Arobi edu Abẹokuta 1930
Rev Father S. Woodley R.C.M Eko 1936.
Madam Flora,I,Elliotte Eko 1940
DR.O Ọbasa of Ikija Eko 1940
Johnson, E Elẹmu Eko 1939
Loya T, E, William: Eko 1938
Dr Da Rocha Eko 1942
Lawani Koffi Eko 1921
Abudu Kadiri Eko 1921

### Ibere

OLOTU

Inu mi yio dun jọjọ bi mo ba le ri ẹniti yio la idi tẹ yemi ti afi npe Isin Igdagbo ni isin Kiriyọ Bawo lo ti se jẹ be.

Emi ni

Xtian.

### Idahun Si Ibere Komolafe

Olotu, Gba mi laye lati dahun si ibere Ọgbẹni Y. A. Komọlafẹ ti o mbere itumọ Ọkunrin kan to di ẹru igi sil, tan, ti ko le gbe nwọn si gbera u, ko le ṣise, ni nwọn ba tun so kalẹ. Bi awọn ti sọkalẹ tan, o be ada, o tun bẹ sigbo, o nge igi si. Tani ẹni na?

Idahun rẹ ni, wipe ẹniti o ngẹ igi ni ọkunrin obinrin si ni igi na.

Bi obinrin ba pọ ju lọdọ ọkọ ko ni le gbọ bukata wọn tan, eyi ni ẹru ti ọkunrin na ko le ru. Botiwu ki ọkunrin ni iyawo to ko le moju kuro lara awọn obinrin ti ode, eyi ni Ọkunrin ti ko le ru ẹru ti a si so ọ kalẹ ti o tun be ada ti o bọ sinu igbo ti o tun nṣegi miran si.

Emi ni
J. Ọlayẹmi

ara Onitsha

## REAL OPPORTUNITY FOR TRADERS

"Iron-Sheets, Cement, Stockfish
All kinds of Beer, Gin,
Salt 40 lbs, Large Sweet mineral
Waters, Flour, 100 lbs, Caustic
Soda, Stout Beer.
Buy the Medicines :-
Jẹdijẹdiand Inarun Bitter Tonics,
Pile Tablets, Cough Mixtures,
Tonics, Quinine mixture, Metatone
Eye drops, Earache drops,
Toothache drops, Worm Expeller,

ASTHMA CIGARETTE

This is good for asthma Bronchitis, Whooping Cough & Shortness of Breath etc, etc.

While assuring you of all our best attention at All times,

Buy the cheapest and Best articles and Medicine from :-

**J. A. AJAO BROTHER**

10, Egerton Road, P. O. Box 358,

Lagos, Nigeria

## IRORA ORIKERIKE

### Ama so ni di alara gigan tabi aro



Nigbati Kidinrin tabi Ọlọ-inu rẹ ko ba ṣiṣẹ re to o yẹ ki a si tan lọwọ. Bi bẹko iwọ papa yio mọ fsore rẹ pe ewu mbọ. Nina awọn ewu na ni irora orikerike jẹ ọkan o le jẹ wipe Ọlọ-inu rẹ ko ṣiṣẹ re to nipa aṣẹ ẹjẹ ara re,

Egbogi DE WITT yi a se nipataki lati jeki Ọlọ-inu re bere si ṣiṣẹ re ibi iranlọwọ ti yio je fun Kidinrin ni lati koko wo gbogbo irora orikerike na fọye. Gbogbo awọn ẹjẹ ti ko tọ nwọn ti o mbe nibe yio kuro,

Ọpọlọpọ iwe ni a ti ngba kakiri aiye ti awọn enia ti dupẹ fun wa latari egbogi DE WITT'S ti ti nwọn si ti ṣiṣe ara wọn gba Boya iru egbogi yi le se rere fun lo dan wo fun iyọnu tire lọ bere ni ṣọbọ egbogi.

Egbogi DE WITT yi ẹ nipatki iun.-



ARUN ABUSGUN WODI EHIN DIDUN IRORA ORIKERIKE LAKURẸGỌ ati gbogbo IRORA

Obun ti o dawa lojo ni wipe egbogi DE WITT'S eyin ti kunitoni gbogbo ohun ti o kọ le si mọ gara,

**DE WITT'S PILLS**
**for Kidney and Bladder Troubles**

### Ile Egbogi To Mbe Ni Owu Ikija Yio Duro

**Ijebu Ode** Awọn igbimọ ti o mbe ni egbegbe ile Ijebu ṣe ipinnu wipe ile ibiti a npo egbogi fun awọn alaisan ti o mbẹ ni Owu Ikija, yio da ise duro, nitoripe, ile egbogi ni ko ti iṣe ṣe tobẹ, nitoripe boya ko si ol kunrun tabi alaisan nilo na ti o nfẹ egbogi oyibo.

Ọlọ ti pe lọjọ ti njba ti efe da ile egbogi na duro, Ṣugbọn Ọgbẹni T. A. Odutola lo ṣe ... ẹni si wipe ki awọn ... duro dẹ fun awọn enia si.

Ọnisẹrun ti ... ile egbogi na ti sọ wipe ... awọn da ṣe egbogi ti o mbẹ ni Owu Ikija duro nitoripe awọn ... fẹ egbogi oyibo.

Awọn ara ... wipe ki a da ... ile egbogi na duro nitoripe agbara ... enia ... fi owo gba egbogi nibe.



# AGBO ABOYUN




Omi D'ajo tu, ẹja tiṣon ọo-ọ, a ghe tara danu, a ghe mirau de idi ra de tun awọn aboyun ati abiyamọ M B T (Magic Blood Tonic) de kurgb-kunnbe lọ! Oyi, Sapdomi, Inurun, Alakala, Qwọ, ati tọọ wuwo Ẹrike, bekan-ẹgbẹkan, airi orun sun, atọ dede ati oriṣiriṣi aisan miran ti o nyọ aboyun iṣẹ, ko le si lori yiiti o ba nlo M B T O si tun dara pupọ fun abiyamọ ti o afẹn ọmọ l'ọmu. Wa ra tire ni 4/6d, owo ọkọ 1/6d 12/- dozen lọdọ wa.

## The Egba Trading Aradan Stores

144, Denton Street, and 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute Metta, 46, Victoria Street, Lagos Phone 44153, a tun wa ni New Motro Park (Ogunpa) Ibadan

## Dance! Dance! Dance!

*to the music of*

**Gallotone RECORDS**



A LARGE RANGE AVAILABLE

*in the happiest month of the year*

obtainable from

**S. C. O. A.**

everywhere in Nigeria.

## Registration Envelopes

IT IS NOTIFIED FOR GENERAL INFORMATION THAT, AS FROM 1ST JANUARY, 1954, A NEW ISSUE OF TWO REGISTRATION ENVELOPES, BEARING 4D STAMPS WILL BE PLACED ON SALE AT ALL POST OFFICES AND POSTAL AGENCIES.

THE ENVELOPES ARE OF TWO TYPES:- "F" SIZE 5¼" X 3½", AND "H" SIZE 9½" X 4", THE SELLING PRICES WILL BE 7D AND 8D RESPECTIVELY.

J. A. PARER,
AG. DIRECTOR,
POSTS AND TELEGRAPHS

## Public Notice

The Lagos—Warri Creek Mail will sail on Saturday the 2nd January, 1954 instead of Friday 1st January, 1954.

(Sgd.) G.N. WOOD
DIRECTOR OF MARINE

# REDIFFUSION

FOR LESS THAN THREEPENCE PER DAY
*you can obtain*

NEWS
MUSIC
EDUCATION
ENTERTAINMENT

FROM 6 A.M. to 11 P.M.

**IN YOUR OWN HOME**

APPLY AT OFFICES IN LAGOS, IBADAN & ILESHA.

## Enjoy Your Own Songs

SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERINGS OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS ON




OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigerian Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIGERIA

Printed & Published by The Union Trading and Publishing Company, 12, Kosoko Street, P.O. Box 4[illegible] Lagos. Phone 2030